AWỌN OHUN PATAKI INU IWE OSẸ YI
Ẹ fi orukọ silẹ fun idibo
Oju iwe 1
Kapenta fẹ da iṣẹ silẹ
Oju iwe 1
Talo jẹbi ninu wọn
Oju iwe 2
A soro sọ bi ọrọ
Oju iwe 3

# IRAWỌ ★ OBOKUN

Ẹ dibo fun Akukọ
Oju iwe 4
Akọle Olotu
Oju iwe 5
Idagbere fun Ajẹlẹ Ijẹṣa
Oju iwe 6
Kini ore ti Ọpẹ se
Oju iwe 7
Kikọ orukọ Idile
Oju iwe 8

Vol 4 No. 161 ILESHA MONDAY. NOVEMBER 7 1955 IYE OWO: TORO

# EGBE GBOGBO KAFINTA NIGERIA FE SI ILE ISE NLA SI ILESA



OLỌLA D. K OLUMOFIN

## IPADE AWỌN ẸLẸRI JEHOFA FẸ BẸRẸ

(Lati Ọwọ Abraham O. Ajimalasan, G 53 Isare St. Ileṣa)

E jọwọ Olotu Irawọ Obokun ẹ gbami laiye lati sọ fun oyinwipe awọn Ẹgbẹ Ẹlẹri Jehovah yio ṣe ipade ni inu ọsẹ yi.

Ipade na yio bere ni ọjọ Alamisi ti nṣe Thursday ọjọ kẹwa oṣu kọkanla ọdun yi.

Ipade na yio jẹ ipade to larinrin lọpọlọpọ, ao ṣe ipade na fun Ọjọ merin.

Alaga Ipade na yio wa lati Ilu Amerika. A bẹ gbogbo enia lati wa si ipade na, lati wa gbọ ọrọ Olọrun nibẹ. Ọfẹ ni ijoko, enikẹni lo le wa sibẹ lati wa gbọ.

Awọn Ẹleri Jehovah ti yio ti ilu miran wa si ipade na yio ju Ẹgbẹrun lọna mẹdogun lọ.

A o ṣe ipade na ni ilu Ileṣa o to oṣu mẹta abọ ti a ti ṣe iru ipade na ni ogbọn 'gbaye tiwọn.

Gbogbo awọn enia lo ti wa nwo ibẹ ti o si nya wọn lẹnu wipe iṣẹ pọ sibẹ Ẹgbẹ aiye titun na wa lẹnu iṣe pẹrẹu.



OLỌLA KỌMỌLAFE

Ninu iwe ti Ogbeni J. O Ọlọwẹ kọ lọṣẹ yi, o dupẹ lọwọ Ọlọrun wa yi ati ọpọlọpọ awọn eleto ilọsiwaju ilu pe wọn ku iṣẹ.

## N C N C YIO ṢI ILE IṢETO ẸGBẸ WỌN

Iwe jade pe NCNC ilẹ Ijẹṣa yio ṣi ile Iṣeto nla ti wọn gba ni Okeṣa lọjọ Satide to mbo. Ọpọlọpọ awọn minista NCNC ni yio wa si ibi aseyẹ na.

Nitoripe awọn alaṣẹ ẹgbẹ NCNC ripe eto pupọ yio wa lọdun to nbọ, wọn ti pinu lati fi ikorita iṣeto ẹgbẹ wọn si Ileṣa.

Ki wọn le ri ile nla to tobi to lati eba iru eto bẹ awọn ẹgbẹ NCNC ẹka ti ipinlẹ Ijẹṣa tigba ile nla ti awọn onibanki (Farmers Bank) ti nlo ri nitosi ile Ọbala ni Okeṣa.

Wọn ti fi iwe si ogunlọgọ enia pataki pe wọn yio ṣi ile na pelu aseye nla ni ọjọ Satide ọjọ kejila oṣu yi lati agogo meji soke.

Diẹ ninu awọn aṣaju NCNC to mbọ fun eto aseyẹ na ni awọn Ọlọla T. O. S Benson, Kọla-Balogun, Adegoke Adelabu, Mbadiwe,

## AWỌN KAPẸNTA FẸ DA IṢẸ SILẸ

Lati nkan bi oṣu meji sẹhin ni ikede ti njade pe awọn ẹgbẹ Kapẹnta ti gbogbo ayika Nigeriå ati Kamarun, pẹlu Oke Okun ati aṣoju lati ilu Oyinbo yio ṣe ipade ni Ileṣa lati ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu to kọja

Nigbati ipade na ti ku ọjọ mẹta ni awọn aṣoju ti nwọlu lati ilu okere. Aṣoju miran wa lati irin ọjọ mẹtala si Ileṣa. Gbogbo awọn aṣoju lati ilu Oyinbo lo kọwe ranṣẹ pe bi o tilẹ jẹ pe awọn ko le wa, sibẹsibẹ awọn faramọ gbogbo ohun ti wọn ba sọ ni ipade ati pe awọn

( Bẹrẹ ni oju iwe 8 )

## E FORUKO SILẸ FUN IDIBO

(Lati Ọwọ Kanselọ S. Akindele Ojo.)

Lati ọjọ kini oṣu yi ni eto iforuko silẹ fun idibo ti bẹrẹ jakejado Ekun Iwọ Orun Nigeria. O dun mi lati ṣe akiyesi pe ogunlọgọ enia ni ko gbọ ṣeti ti ko si mo rara pe eto kankan nlọ lori iforukọsilẹ fun idibo.

Ohun to fa eleyi nipe kosi ikede to nipa eto iforukọsilẹ na.

Lasiko ti wọn fẹ ta ayo orire nijọsi awọn olukede ijọba gbe moto olugbohun wọn sode nigbana lati fi kede re. Gbogbo enia lo ri bi eto ayo orire na ti ni iyọrisi dada to

Eto iforukọ silẹ fun idibo yi ni ohun ti emi rope o ṣe pataki ju ohun gbogbo lọ, Idi nipe eto iforukọsilẹ fun idibo yi ni igbesẹ kini nipa igbekalẹ eto iṣejọba. Ni iwọn igbati olukede ijọba ti le fi moto wọn kede eto tita ayo orire fun awọn Ẹgbẹ Alagbelebu ti mo rope ko kan wọn lọwọ, ko kan wọn lẹse, emi ko ri idi ti wọn ko fifi moto olugbohun wọn kede eto iforukọsilẹ yi si eti igbọ gbogbo enia

Ohun to tunbọ jẹki iru ikede bẹ ṣe pataki nize awọn obirin ti ko foruko silẹ fun idibo ri debi ti wọn tilẹ ma dibo rara ni lati lọwọ ninu iforukọ silẹ fun idibo na nitoripe awọn na ni lati dibo.

Ti o ba kuku jẹpe ijọba ko fẹ ki wọn dibo ki wọn kuku sọ. Idi ti mo fi sọ bẹ nipe ogun ọgọ obirin ni eto iforukọ silẹ na ko fi aye gba lati forukọ silẹ. Fun akiyesi obirin ki i san owori, tabi owo omi, tabi owo ina, tabi owo ẹkọ, tabi ti iwosan jake jado ọpọlọpọ ipinlẹ ni Ekun Iwọ Orun Nigeria.

Ko si ipinlẹ ti a le ri ti awọn ajoji obirin to wa nibẹ ko ni fẹrẹ to idamẹrin (One quarter) gbogbo

(Bẹrẹ ni oju iwe 5)



J. M AJAYI-OBE

Ninu iwe ti Akindele Ojo kọ lọṣẹ yi, o ni loju alagba yi awọn miran ni on ṣe afi iwe iforukọsilẹ to ti gbọna ojoro dọwọ Ọlọpẹ han eleto iforukọsilẹ ni Ileṣa.

## WANTED

EITHER a graduate with teaching qualification OR, a Holder of Professional or Grade I Teachers' Certificate with requisite experience as Principal for, Ijesha Divisional Teacher Training College, Ilesha to take up appointment as from 1st January, 1956.

All applications should be directed to the Chairman' Board of Governors, I. D. T. T. C., Box 34, Ilesha and to reach him not later than 19th November, 1955.

SECRETARY, BOARD OF GOVERNORS.

## World Conquest Soon

BY GOD'S KINGDOM

HEAR PUBLIC ADDRESS BY

M. G. HENSCHEL

representative of Watch Tower Society on Sunday, November 13, at Jehovahs Witnesses' Booth, Igbaiye Quarter, Ilesha.

ALL WELCOME NO COLLECTION

# IROHIN LATI AGBEGBE

## GBIMỌ IJẸBU-JẸṢA DA GBERE FUN MACKENZIE

(Lati Ọwọ Kansẹlọ J. B. Awẹ)

Ni ọjọ Alamisi eyiti iṣe ogunjọ oṣu to koja, Igbimọ Ijẹbu-Jẹṣa dagbere fun Ajẹlẹ wa ti o lọ si ilu rẹ, awọn tun ki Ajẹlẹ titun Ọgbẹni A. F. Meed kabọ.

Eyẹ na bẹrẹ ni dede agogo mẹji abọ ọsan. Alaga igbimọ yi, Ọgbẹni B. O. Omoke ka awọn Ajẹlẹ na sọrọ. Ninu iṣọrọ rẹ ni o ti fi han gbogbo ijoko iru iṣẹ ti Ajẹlẹ wa Ọgbẹni K. Y. M. Mackenzie ṣe si ilẹ Ijẹṣa papa Ijẹbu-Jẹṣa. Pẹlu aya rẹ lo jẹki a le kọ ile alabiyamọ (Maternity) si ilu Ijẹbu-Jẹṣa.

Alaga tun fi yeni ninu ọrọ rẹ wipe Ajẹlẹ na ni ọgbọn ati oye ti o fi ma npa iwa buburu mọ awọn olusẹ buburu ninu ati pe ọsẹ ṣiṣẹ lo fi Ijẹbu-Jẹṣa ṣe ki iṣẹ aye bi oniṣẹ lo nbawa lo nitoripe ni asiko kan ti ede aiyede wa larin alaga ati Ogboni Ijẹbu o pe wọn ṣegebi ọrẹ sọrẹ ni ile rẹ, o ba wọn sọrọ lai jẹki enikẹrin pẹlu wọn nibẹ ati ibikib si enia batiri ni, o setan lati ṣiṣẹ, akoko kakoko lo ṣetan lati feti si awawi tabi ifisun kifisun ti awọn ba mu tọ wa.

O tun sọrọ nipa owo'ri gbigba, o fiye wa pe lati igbati Ajẹlẹ yi tide lo ti nlo ọfiṣiriṣi ọgbọn lati ripe owo'ri rọrun lati ma gba. Bi o tijẹ pe oju ọna si awọn ilu ti o yi Ilesa po ko dara yẹn, Ajẹlẹ ko ka wọnyi si rara bi o tiwu ki ilu na jina to yio de ibẹ.

O Nigbati o wa nlọ yi, o nfi ilu wa silẹ ni aye ti o dara ju bi o ti ba lọ.

Lẹhinna ni Alaga wa mẹnu ba ọrọ die nipa ti Ajẹlẹ titun to ti gbọ bi a ti jihin iṣẹ Ajẹlẹ ti o nlọ. O ni ki ṣepe a npọn rara, bi iṣẹ rẹ titi niyẹn. Nitorina ki iṣe pe onijangbọn ni wa o ṣugbọn igbakugba ti iruju ba de ti a ba wa ba ki o jọwọ ki o gbawa tiyi tẹyẹ.

Ọgbẹni Machenzie wa dide o dupẹ pupọ o si fi yẹ wa pe ki sẹ igbimọ ti wa lo dara julọ ni gbọgbọ ilọ Ijẹṣa nitorina ki a maṣe sun rara nipa ti Igbimọ na, Ki awọn oloye wa gbogbo mọ dajudaju pe akoko ti yi pada ki awọn ma si ba yipada nitoripe kiṣe akoko yi ni Ijoye kan ma npepe "Ati emi A fi eni"

Nitorina o gbawa niyanju pe ki awa Kansẹlọ ati awọn Ijoye lọ fọwọ sowọ ki a si jẹki iwa Igbagbo ati iṣe ohun rere sowa pọ ki a ma ṣe tan ẹnikẹni jẹ rara.

Lẹhin eyi ni Ajẹlẹ titun, Ọgbẹni Meed dide to dupẹ pupọ fun pipe ti a pe on lọjọ na. O tun gbawa niyanju pe ki a lọ ọwọsowọ, bi a ko ba ṣe eyi o mi a jẹpe a sọ awọn ti o yan wa sinu iya niyẹn.

O fun wa ni idaniloju pe on ṣetan lati ran wa lọwọ bi a ba fi ara wa ṣe ọkan.

Lẹhin eyi ni olutọju Alabiyamọ (Nurse) Miss R. O. Oni wa gbe iwe ti awọn Igbimọ yi ti pese silẹ fun Ajẹlẹ ti o nlọ lati le ma fi ranti asiko rẹ larin wa fun.

Arabirin Oni tun fun Ajẹlẹ na lẹbun t'on fun rarẹ.

Lẹhin eyi ni Ogboni wa dide to o dupẹ lọwọ aya Ajẹlẹ ti o nlọ fun iwa rere rẹ ki o to le fun ọkọ rẹ ni iwa rere rẹ ki o to le ṣiṣẹ tọkantọkan.

Awọn ti o wa nibẹ ni Ọlọla Olu Komolafẹ, Ọgbẹni Afilaka, Adeniren, Okunwọle, Awẹ, D. F. A. Aribisala, Oloye Saba Ijẹbu, Aro, Osogun, Risawẹ, Saba Ẹsa-Oco, Ayọde, ati Omidan Tọbalawi.

Bayi la pari idagbere yi ni dede agogo mẹta ọsan.

---

## S. IṢỌLA GEORGE F'EGBẸ ỌPẸ SILẸ

Eyi ni lati sọfun gbogbo agbaiye gbọ pe ẹniti orukọ rẹ wa ni isalẹ iwe yi, ti mo ti jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Action-Group tẹlẹ ri, ti fa ọwọ mi yọ lati oni kuro ninu ẹgbẹ Olọpẹ Emi ko ṣe Ọpẹ mọ o.

Emi ni Ebenezer Sunday Isọla George.

AKỌLE OLOTU: A bẹ Iṣọla George ki o maṣe binu pe a ko gbe iwe on jade lasiko. Lati ọjọ kẹta oṣu September-1955 lo ti kuro ninu ẹgbẹ na o si fi ẹda iwe rẹ sọwọ si ọpọlọpọ awọn to kan.

---

## IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ra Irawọ Obokun ni Ẹrinmọ ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogundele, Ọna Ẹffọn No 644 Ẹrinmọ.

---

## FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ N.C.NC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.



KANSẸLỌ M. I. EKUNDARE

Ninu ọrọ ti Akindele Ojo sọ lose yi, o ni o ṣe oju Ọgbẹni wa yi ati awọn miran nigbati on fi iwe iforuko silẹ ti on bẹbẹ gba ninu eyiti o ti dowẹ Olori ile iwe kan ni Ibodi, eyiti o sọ pe wọn fi nforukọ Ọmọ Ẹgbẹ Ọlọpẹ silẹ ni bokẹlẹ.

---

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

